# AWỌN IṢẸ IYANU TI IWOSAN --- BÍBÁ AFẸFẸ ATI ÒKUN WÍ

**Johannu 4:46-54; Marku 2:1-12; Matteu 8:1-27**

**ẸKỌ 32 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Adura igbagbọ́ yio si gbà alaisan na là, Oluwa yio si gbé e dide" (Jakọbu 5:15).**

## Igbagbọ́ Ọkunrin Ọlọla Kan

Jesu n ṣe rere fun awọn eniyan nibikibi ti O ba lọ. Ọpọ eniyan maa n pejọ pọ sọdọ Rẹ nigba ti wọn ba ri i pe O wa ni tosi, Oun ko si ta ẹnikẹni nù rí. Ohun ti Jesu n fẹ ni pe ki awọn eniyan ni igbagbọ́ ninu Oun. Bawo ni Oluwa wa yoo ti ṣe ohun nla fun wa to nigba ti a ba gbagbọ́!

Ọkunrin ọlọla kan ni ọmọ ti ara rẹ ko dá, o si gbagbọ́ pe Jesu le wo o san. Òótọ́ ni pe o jẹ ọlọla ati boya o jẹ ọlọrọ pupọ ṣugbọn eyi ko ran an lọwọ nigba ti aisan wọle tọ ọ wa. Ọpọlọpọ awọn ọlọrọ ni wọn ti fun onişegun aye ni gbogbo ọrọ ti wọǹ ni bi o ba le wo ọkan ninu awọn olufẹ wọn san; ṣugbọn nigba ti Baba wa ti n bẹ ni ọrun ba wi pe akoko to lati ku, kò si owo ti o le fun onişegun ni agbara lati fa ẹmi naa gun (Oniwasu 8:8; Jobu 14:5).

Ọkunrin ọlọla yii gbọdọ ti gbagbọ́ pe Jesu ni agbara lati ṣe iṣẹ-iyanu, ṣugbọn o ro pe Jesu ni lati ba oun lọ si ile. Boya ko ti i gbọ ri pe Jesu le sọ ọrọ, ki ohun naa si ṣẹ, bi o tilẹ jẹ pe O wa ni ọna jijin.

Jesu ko gbogbo awọn ti o wa nibẹ pọ̀ nigba ti O wi pe, "Bikoṣepe ẹnyin ba ri ami ati iṣẹ iyanu, ẹnyin ki yio gbagbọ́ lai."

Wọn ki yoo gbagbọ bi ko ṣe pe wọn ba le ri ami. Ṣugbọn eyi ki i ṣe igbagbọ́. Paulu wi pe, "Ireti li a fi gbà wa là: ṣugbọn ireti ti a ba ri ki iṣe ireti: nitori tani nreti ohun ti o bá ri?" (Romu 8:24). Lati gba ohun ti a ko ri gbọ ni a n pe ni igbagbọ́. Abrahamu ni igbagbọ́ nla, nitori o gba Ọlọrun gbọ́ Ẹni ti "O si pè ohun wọnni ti ko si bi ẹnipe nwọn ti wà;" (Romu 4:17). Bi a ti ka ori kọkanla iwe Heberu, a mọ ohun ti igbagbọ́ jẹ, ati ohun ti o le ṣe. Awọn akikanju ninu igbagbọ́ ti a darukọ nibẹ gba awọn nnkan ti o ṣoro lati ri gbọ́. Jesu n fẹ ki awọn ara Galili wọnyi ni iru igbagbọ́ kan naa.

## A Wo Ọmọ Rẹ Sàn

Nigba ti ọkunrin ọlọla naa gbọ́ ti Jesu wi pe, "Mã ba ọna rẹ lọ; ọmọ rẹ yè," o gbagbọ́, o si ba ọna ti rẹ lọ. Bi a ba lo igbagbọ́ kekere ti a ni, ki a si duro lori awọn ileri Rẹ bi o tilẹ jẹ pe a ko le ri ohunkohun, Ọlọrun yoo fun wa lere, yoo si busi igbagbọ́ wa.

Awọn iranṣẹ ọkunrin ọlọla yi pade rẹ, oun si ri i pe ọmọ oun ti bẹrẹ si i san ni wakati kan naa ti Jesu wi pe, "ọmọ rẹ yè." Gbogbo ẹbi naa ni o gba Jesu gbọ́ nigba ti wọn ri iṣẹ-iyanu yii. Nigba miiran, awọn eniyan lode oni ki i fẹ gba Jesu gbọ bi o tilẹ jẹ pe wọn ri abayọrisi adura ati igbagbọ́.

## Ọkunrin Alarun Ẹgba

Awọn Farisi ati awọn amofin paapaa wá lati gbọ ẹkọ Jesu, ṣugbọn wọn wá lati ri wí si I pẹlu. Jesu ko dẹ ọrọ Rẹ tabi din in kù ki o ba le wu wọn. Iwe Mimọ sọ pe O waasu gbogbo ọrọ naa fun wọn. Jesu n fẹ ki awọn alufaa Rẹ ṣe bẹẹ gẹgẹ. Nigba ti Jesu waasu Ọrọ naa "agbara Oluwa si mbẹ lati mu wọn larada" (Luku 5:17). Paulu sọ fun Timoteu pe, "Wasu ọrọ na, ṣe aisimi li akoko ti o wọ̀ ati akoko ti ko wọ̀; baniwi, ṣe itọ́ni, gbani niyanju pẹlu ipamọra ati ẹ̀kọ́ gbogbo" (2 Timoteu 4:2). Nigba ti a ba waasu Ọrọ naa bayi, agbara Ọlọrun yoo tẹle e lati gba ọkan la ati lati wo alaisan san. "Ami wọnyi ni yio si ma ba awọn ti o gbagbọ́ lọ; Li orukọ mi ni nwọn o ma lé awọn ẹmi eṣu jade; … nwọn o gbé ọwọ le awọn olokunrun, ara wọn ó da." (Marku 16:17, 18).

Nigba ti ọpọ eniyan pejọ pọ sọdọ Jesu ninu ile, awọn ọkunrin mẹrin gbe ọrẹ wọn kan wa ti ara rẹ ko da to bẹẹ gẹ ti wọn ni lati gbe e lori akete tabi ibusun. Wọn ni igbagbọ pe bi awọn ba ti le gbe e de ọdọ Jesu, a o wo olokunrun naa san. Wọn ko le la aarin awọn ọpọ eniyan naa kọja, ṣugbọn igbagbọ́ wọn ri ọna miiran. Wọn gun ori orule ile naa wọn si gbé ọkunrin alaisan naa soke pẹlu wọn, wọn da orule ile naa lu, wọn si sọ ọ kalẹ si iwaju Jesu gan an. Inu Jesu dun lati ri igbagbọ́ wọn, O si wo ọkunrin alaisan naa san.

Jesu n fẹ iru igbagbọ́ bẹẹ ninu wa. Oun ko fẹ ki ohunkohun di wa lọwọ ni gbigbẹkẹle E. O ti wi pe bi iwọ ba saa ti le gbagbọ́, iwọ yoo ri ogo Ọlọrun. Bawo ni yoo ti ba A lọkan jẹ to nigba ti a ba n ṣiyemeji Rẹ, lẹyin awọn ileri iyanu ti O ti fun wa! Lai si igbagbọ́ o ṣoro lati wu U.

Ọpọlọpọ igba ni a n jẹ ki awọn nnkan kékèké di wa lọwọ lati má jẹ ki adura wa lọ sọdọ Ọlọrun. Boya a n ro pe ọwọ wa dí pupọ lati gbadura; tabi ki a jọgọ nu bi a ko ba tete ri idahun si adura wa gba. Ṣugbọn igbagbọ́ yoo di odi mu titi iṣẹgun yoo fi dé, bi o tilẹ jẹ pe a ni lati "gun ori orule, ki a si sọ ara wa kalẹ lati ori aja ile lati ri Jesu."

**“A Dari Ẹṣẹ Rẹ Ji”**

Jesu wo ọkunrin yii sàn ni ọna ti o yatọ si bi O ti n wo awọn miiran sàn. Ẹnu ya awọn eniyan nigba ti wọn gbọ ti o wi pe, “Ọmọ, a dari ẹṣẹ rẹ ji ọ,” ṣugbọn bawo ni inu ọkunrin alarun ẹgba yii yoo ti dun to lati ri igbala ati iwosan lẹsẹ kan naa! Boya ko tilẹ ronu nipa ẹṣẹ rẹ ri, ati bi wahala ti wọn ti fun un ti pọ to. Ṣugbọn Jesu le ri i pe ifẹ kan wa lookan àya rẹ̀ lati ṣe ohunkohun ti Oluwa n fẹ ki o ṣe, nitori naa ni O ṣe fun un ni ibukun ilọpo meji. O beere, “Ewo li o ya ju lati wi … A dari ẹṣẹ rẹ ji ọ, tabi lati wipe, Dide, si gbé akete rẹ ki o si ma rin?” Jesu fẹ ki wọn mọ pe Oun le dari ẹṣẹ ji pẹlu, ki wọn le gbagbọ́ pe Ọmọ Ọlọrun ni Oun I ṣe – nitori wọn mọ pe Ọlọrun nikan ni O le dari ẹṣẹ ji.

Ṣugbọn awọn akọwe, ti ọkan wọn kun fun ariwisi, ko le ri agbara Ọrun Rẹ̀ wọn si sun Un ni ẹsun pe O sọ ọrọ odi. Iba ṣe pe wọn mọ pe Ẹni keji ninu Mẹtalọkan ni Oun i ṣe! Iba ṣe pe wọn le ni ọkan ootọ ti o n fẹ gbagbọ́, Jesu iba ti fun wọn ni ibukun iyanu pupọ pẹlu. Ẹni ti o ba gbagbọ nikan ni o n ri ibukun Kristi gba. Ọkunrin alaisan yii ko ṣe aisan mọ́; o gbe akete rẹ o si lọ si ile rẹ, o di ẹda titun ninu Jesu Kristi.

Ninu ẹkọ yii, a n ṣe aṣaro lori awọn iṣẹ-iyanu nipa eyi ti Matteu sọ fun wa. Lẹyin iwaasu Jesu lori oke, ọpọ ijọ eniyan tọ Ọ lẹyin, awọn miiran si gbagbọ́. A ṣe akiyesi pe kiki awọn ti wọn ba gbagbọ́ ni wọn n gbadun anfaani Kristi.

O ti di aṣa awọn Farisi lati maa wa ẹṣẹ si Jesu lẹsẹ nipa ọrọ ofin; ṣugbọn lẹyin ti O ti wẹ adẹtẹ ni mọ́, O ran an lọ sọdọ alufaa lati lọ ṣe irubọ ti Mose ti palaṣẹ ninu Ofin. Bi a ti n kọ ẹkọ nipa igbesi aye Jesu, a ri pe O ṣọra pupọ lati gbọran si Ofin: ofin atọwọdọwọ eniyan ni Oun ko naani, eyi ni o si bi awọn agabagebe ninu (Marku 7:5). Sibẹ Jesu wi pe Oun wa lati mu ofin ṣẹ. Nigba ti O pari iṣẹ Rẹ̀ ninu aye O di Olori Alufaa wa, a ko si fẹ ofin mọ́ (Ka Heberu 9).

**Imọlẹ Fun Gbogbo Eniyan**

Nigba ti balogun ọ̀rún wa sọdọ Jesu o fi igbagbọ́ ti o ya ni lẹnu hàn. Ijoye ara Romu ni oun i ṣe, ko si si ẹni ti yoo ni ireti pe o tilẹ le gba Jesu gbọ rara. Ṣugbọn imọlẹ Ihinrere ti fara han fun gbogbo eniyan, a ko le ri ibukun gba lọwọ Ọlọrun lori pe a bi wa ninu ile Onigbagbọ, ṣugbọn nitori pe a gbagbọ́ fun ara wa ni.

Jesu wi pe, “Emi ko ri igbagbọ́ nla bi iru eyi ninu awọn enia Israẹli.” Itumọ eyi ni pe awọn Ju, awọn eniyan ti Rẹ̀, ko gba A gbọ́ gẹgẹ bi ọmọ-ogun ara Romu yi ti ṣe. A ti ka a pe Ọlọrun yan Abrahamu, Isaaki ati Jakọbu lati jẹ ọmọ Rẹ̀, O si ṣeleri pe lati inu iru-ọmọ wọn ni a o ti bukun fun gbogbo orilẹ-ède aye; ṣugbọn O wi pe nisisiyii awọn alejo yoo wá lati ila-oorun ati iwọ-oorun wọn yoo si wọ ijọba ọrun ṣaaju awọn ayanfẹ Rẹ̀ ti wọn kò gbagbọ pe Jesu ni Messia naa. Awa ti a jẹ Keferi, ni “awọn alejo” naa ti o le wọle, ki o si gba ibukun Ọlọrun nipa igbagbọ́ bi a ba gbagbọ́.

Ọpọlọpọ awọn alaisan ati awọn ẹlẹmi eṣu wa sọdọ Jesu, O si wo gbogbo wọn san. Isaiah ti sọ asọtẹlẹ pe, “On tikararẹ̀ gbà ailera wa, o si nrù àrun wa.” Jesu n fẹ wo wa san nigba ti a ba ṣe aisan, O si ti sọ ninu ọrọ Rẹ̀ pe, “Egbe ni fun ẹniti o gbẹkẹle enia, ti o fi ẹlẹran ara ṣe apá rẹ̀, ẹniti ọkàn rẹ̀ si ṣi kuro lọdọ Oluwa!” (Jeremiah 17:5). Bi a ba lọ sọdọ awọn oniṣegun ayé fun iwosan, a n ṣako kuro lọdọ Oluwa ni, Oun ko si ni inu didun si wa. Ninu Orin Dafidi 50:15, a ka a pe: “Ki o si kepè mi li ọjọ ipọnju: emi o gbà ọ, iwọ o si ma yìn mi logo.”

**A Bá Igbi Wí**

Lẹyin gbogbo iṣẹ oore wọnyii ti Jesu ti ṣe, aarẹ mu Un; nigba ti Oun ati awọn ọmọ-ẹyin si wọ inu ọkọ lati bọ si odi keji okun, O si sùn. Igbi nla dide, ẹru si ba awọn ọmọ-ẹyin pe awọn yoo rì. Wọn gbọdọ ti ni igbagbọ́ ninu Jesu nitori wọn kigbe pe, “Oluwa, gbà wa.” Ṣugbọn nitori pe ẹru ba wọn, O wi pe, “Ẹnyin onigbagbọ́ kekere.” Ọlọrun n fẹ ki awọn ọmọ Rẹ̀ gbẹkẹle Oun, ki wọn má si ṣe bẹru. “Ifẹ ti o pé nlé ibẹru jade:” (1 Johannu 4:18).

Nigba ti Jesu ba afẹfẹ wi ti igbi si dakẹ, ẹnu ya awọn eniyan pe afẹfẹ ati okun paapaa gbọ ti Rẹ̀. Kò ye wọn pe Oun ni O ti da wọn ni atetekọṣe, ati pe iṣẹ ọwọ Rẹ̀ gbọdọ gbọ ti Rẹ̀.

Awọn Onipsalmu jẹ eniyan Ọlọrun. Ẹmi Ọlọrun ni o mi si wọn lati kọ ootọ nipa agbara Ọlọrun. Boya awọn Ju ti ka Orin Dafidi 89:9 nigbakuugba: “Iwọ li o jọba ibinu okun: nigbati riru omi rẹ dide, iwọ mu u pa rọrọ.” Ati Orin Dafidi 107:29 “O sọ iji di idakẹ-rọrọ, bẽni riru omi rẹ duro jẹ.” Ṣugbọn won kò mọ̀ pe Ọmọ Ọlọrun wa nibẹ pẹlu wọn. Jobu, ẹni ti o jẹ wi pe boya ko ti i ri okún ri, sọ nipa imisi Ọlọrun wi pe “Tali o fi ilẹkun sé omi okun mọ́, ti o si wipe, Nihinyi ni iwọ o dé, ki o má si rekọja, nihinyi si ni igberaga riru omi rẹ yio gbe duro mọ” (Jobu 38:8, 11).

Oluwa wa jẹ Olugbala ti n ṣe iṣẹ-iyanu ninu gbogbo ohun ti O ṣe ninu aye, ninu igbesi aye eniyan ati ti ẹdá; awa si mọ̀ pe ọkan naa ni Oun lonii nitori a kọ ọ pe: “Jesu Kristi ọkanna ni li aná, ati li oni, ati titi lai” (Heberu 13:8).

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni iṣẹ iyanu keji ti Jesu ṣe?

2 Bawo ni a ṣe ṣe ariwisi si Jesu lẹyin ti O wo ọkunrin alarun ẹgba nì san?

3 Njẹ Jesu mọ ero wọn?

4 Bi awọn alaisan wọnyii kò ba ni igbagbọ, njẹ a le wò wọ́n sàn?

5 Bawo ni Jesu ṣe jẹ ki o ṣe e ṣe fun wa lati ri iwosan?